**Lakaye Oro**

Iwọ ọrọ mi, sa otitọ ma si se ta a. Ra ọgbọn, ẹkọ ati imoye, Olododo yio yọ yio si ma pọ si.

Ọmọ ti o ba gbọn yio mu inu baba rẹ d u n, nigbana ni ẹnyin o si mọ otitọ otitọ na yio si mọ yin. ẹ o si di ominira

# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

2 Advance Apprentices 2 Apprentice Printers Apply in Person to:–

TWIN PRINTING PRESS 32 TOKUNBOH STREET, LAGOS NIGERIA.

VOL. V No. 305 MONDAY NOVEMBER 27 — DECEMBER 3 1961 KOBỌ MEJI (2d)

# Iku ko mọ ẹni ọwọ, Iku pa Akọbi ati Abigbẹhin nişoju Iya wọn nigbakanna

OGOJA:– A GBỌ WIPE NṢE NI IYA KAN JOKO TI O NWORAN NIGBATI ỌKAN NINU ỌMỌ RẸ OBINRIN FI NPỌKA I K U, TI GBOGBO AWỌN ARA ILE ATI ALADUGBO BẸRẸ SI DU ỌMỌ IYA NA GBA.

NIBITI WỌN NDU TI AKỌKỌ GBA LỌWỌ WIPE KI O MAṢE KU, ŞIBẸSIBẸ TI O KU, BẸNI ỌMỌ IYA NA KEJI DIDE FUYA O SARE LỌ SIBITI EKEJI RẸ KU SI, O SI BẸRẸ SI SỌKUN TITI TI KO FI LE DIDE MỌ.

Awọn ara ile rope bi ekeji ẹniti o ku na tişẹ ni ko d a r a wọn lọ lati lọ gbe kuro şugbọn nigbati nwọn gbe kuro, on na papa ti ku. Iya ti o bi awọn ọmọ na ri gbogbo ohun ti o şẹlẹ, nigbati ko mọ ohun ti yio şe mọ, o k u k u joko s i l ẹ, o si nwo işẹ Ọlọrun.

Dọkita sọ wipe ijaiya lo pa ọmọ ti akọkọ, arẹ lo si pa ọmọ k e j i. Ibeji ni awọn mejeji, ibi kanna ni nwọn si mu wa si aiye.

## Dokita Lambo gba ebun Alukurani

Ọkunrin Onişegun kan ti o kọ i ş ẹ nipa ọpọlọ enia ti o si ti nwo awọn asinwin san ti orukọ rẹ njẹ A b u d u Rahaman ara ilu Mauritius ni a gbọ wipe o fi iwe M i m ọ Alukurani ta Dọkita T. A. Lambo lọrẹ fun işẹ ribiribi ti o ti nşe nipa awọn ti ori rẹ yi. A gbọ wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ akẹkọ ti wọn lọ kẹkọ fun ilọsiwaju ilu wa ni ilu Oyinbo tabi ni ibomiran ni a gbọ wipe ori wọn yi lọhun.

Şugbọn ko si ẹniti Ijọba Iwọ Orun ko da pada wa sile. Dọkita Lambo ni Onişegun ti Ijọba Iwọ Orun gba lati ma bojuto awọn ti ori w ọ n yi tabi ti n w ọ n di Asuşekan.

## Othman Dan Fodio

Uthhman Dan Fodio ku lọdun 1817, ohun ti o mu wa kọ nipe fun aşitẹ ti a şitẹ nipa rẹ ninu iwe wa ti ọsẹ tokọja.

## Gomina Iwo Orun, Ololа Adesoji Aderemi fe so ilu Mushin di atata

Ọlọla Adesọji Aderẹmi tişe Gomina ipinlẹ Iwọ Orun sọ fun awọn enia ti o ngbe Muşhin ati agbegbe rẹ pe, on yio sọ ilu Muşhin di awo ma moju kuro. Ọlọla A d e s ọ ji sọ bẹ nigbati o lọ şe abẹwo agbegbe Ikẹja. On pẹlu Anaşhin (Iyawo) Ọba lojijọ lọ sibẹ, o ni on fi ara mọ imọran ti Igbimọ Ikẹja ba on da wipe ki on tun Ikẹja ati Muşhin se daradara ki o le dara ni wiwo fun ajeji. Ki o si jẹ Ilu ti a o kọkọ ma gbadun ki a to wọ ilu Eko.

Ọba na pitan fun awọn Igbimọ ti o wa yẹsi na o mu wọn ranti iru ipo ti Muşhin ti wa ri ati iru ipo ti o wa nisisiyi, gẹgẹbi o ti jẹ wipe ilu Muşhin ni a o kọkọ tẹ mọlẹ ki a to de ilu Eko, on yio sọ fun ijọba nigbati on ba pada de Ibadan pe ki nwọn tun Muşhin şe.

O fi ẹnu kan wipe Muşhin jẹ ilu ati ibi ihamọ fun awọn ọmọ ọsọlẹ ati awọn arufin, ko dara ki a ma gbọ itan bayi si ilu ti a pe ni arole Eko. Inu Ijọba yio dunbi awọn ara ilu Muşhin ba lesẹ iranlọwọ fun Ọlọpa bi nwọn ba ri aladugbo wọn ti nşẹ si ofin Ijọba.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Gomina ipinlẹ iwọ orun Ọ l ọl a Adesọji Aderẹmi nigbati o lọ şe abẹwo ile işẹ ibiti nwọn gbe şe ọti Pepsi-Cola ni agbegbe Muşhin eyiti o jẹ ti awọn ẹgbẹ Western Nigeria Development Corporation. On pẹlu Olori iyawo rẹ lo jijọ wa On lo gbe igo ọti kan dani ninu aworan yi. Ẹniti o duro lọwẹ osi rẹ ni Ọgbẹni B. Dawodu tişe Olotu ile işẹ ọti na.

# ỌRỌ OLOTU

## Bi ako ku ise ko tan, sa ti gbe okan re le Oluwa Eleda re

Ohun ti o fa ẹṣin ọrọ wa ti ọsẹ yi ni pe, ojojumọ ni ẹnyin Onkawe wa yio ma ri ka nipa awọn enia ti o nlọ binu Pokunṣo, kini iwọ lero pe o nfa iru aṣa bayi? ohun ti ẹnyin ọlọgbọn yio ti mọ ohun ti o fa nipe, nipa riro igbesi aiye wọn pin, yala aini o w o lọwọ tabi aiko ri ọmọ bi, papa julọ ki gbogbo nkan ma lọ dede fun Oluwa rẹ, on lo fa iru aṣa bayi, nitorina ni aṣo lẹ ṣọrọ diẹ nipa rẹ lọsẹ yi.

Ọlọrun Ọba ti ṣe iṣẹ rẹ pari lara awa ẹda, ki o to da wa si ile Aiye Bi araiye bari ẹniti koiti lowo tabi ki oluwa rẹ bimọ, aropin ni wọn o ma ro si. Ṣugbọn ohun kan ni a fẹ ki ẹnyin Onkawe wa mọ daju, on na ni wipe, ẹniti ko ba iti ku, ti ko si ti fi ile aiye yi silẹ, iṣẹ rẹ nile aiye koiti tan, bi o ba pẹ titi ti enia ti njẹ ẹran, bi oluwa rẹ ko ba ti ku daṣodaju li ọjọ kan ni yio tobi to erin. Ọjọ jijẹ, ọjọ mimu, ọjọ airi jẹ ati ọjọ ibaanjẹ Ọlọrun aṣe gbogbo rẹ, bi o ti wu ki onjẹ wọn to era ti o nrin nilẹ yio ri tirẹ, bi o si ti wu ki omi wọn to, baluwẹ yio ri tirẹ mu, ohun kan ti a fẹ ki o ye yin ni wipe ika ko dọgba. Ẹniti ko ti ku, koiti kọja ẹniti o le di Milọnia, ẹniti o si nfi ẹsẹ rin ko ti kọja ẹniti o le ma fi mọto ṣe ẹsẹ rin.

Iwọ ṣa gbẹkẹ le Ọlọrun Ẹlẹda rẹ, duro sori otitọ ati ododo, yio si dara fun ọ. Nigbati ẹmi rẹ si mbẹ laye, yio dara f u n ọ, dajudaju ranti wipe igba mẹta ni igba igbesi aiye ọmọ enia. Igba owurọ, igba ọsan ati igba alẹ. Bi enia ko ni o w o lowurọ bi ko ba iti ku, o le ni ni igba ọsan, o le ni ni asiko aṣalẹ, awọn ẹlomiran a ma ni owo ni igba mẹta, ẹlomiran a ma ni lọsan ati lasiko aṣalẹ.

Adura awa O n i w e Irohin Imọlẹ ni wipe ki aṣalẹ wa san wa ju owurọ lọ, ma jẹki a rahun ka to jẹun, nitorina bi a ko ba iti ku, dajudaju iṣe ko iti tan. a bẹ gbogbo ẹnyin Onkawe wa, ẹ ma ṣe ma ro ara yin pin, nigbati ẹmi ba ṣi wa, ireti yin ṣi mbẹ.

## Awon ti o sese bo lati ogun Kongo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ Ogun i l ẹ Naijiria ti nwọn lọ ja ogun nilẹ Kongo. A gbọ wipe oṣu kẹfa ni yi, ti wọn ti lọ si ilẹ Kongo, awọn na ni a nwo wọnyi nigbati wọn pada de lati ogun na.

## Gbagidari Igi da!

Lati Ọwọ:— SANNI ERIN

Olotu/ Jọwọ gba mi laye lati ba ọmọ I g b o m i n a sọrọ, ati lati ṣipaya ọrọ si awọn to nreti lati gbọ ọrọ emi Sanni Erin. Mo ki gbogbo awọn ọmọ Igbomina ti wọn nṣe ibere lọwọ emi ti nwọn si fẹ mọ boya otitọ ni mo ti faramọ, ẹgbẹ Ọdọ titun to fi ara mọ ẹgbẹ Olomi ti wọn ṣẹṣẹ da silẹ?

Mo wa fẹ fi eleyi ye awọn enia wa wipe ẹgbẹkẹgbẹ to ba jẹ ẹgbẹ Oṣelu ti emi Sanni Erin ba wa gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ fun irufẹ ẹgbẹ bẹ mo ni lati kede sita fun gbogbo araiye gbọ. Eleyi ni lati wa fi ye yin bakanna wipe lati ẹhin wa mo ti fi igbakan lodi si ẹgbẹ Ọdọ to fi ara mọ Olomi ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ na ṣugbọn lẹhin iwadi pataki ti mo ti nse lẹhin ti wọn ti da ẹgbẹ na sile mo ri ohun to wuni lori fayọ ninu imọ ẹgbẹ na nitoripe ero ẹgbẹ na ati eto wọn lo le fun wa ni anfani ati le gba Division ni ilẹ Igbomina Pẹrẹ Pẹrẹ ọrọ lori eleyi odi Ọjọ mẹjọ.

Ṣugbọn sibẹsibẹ na nko ṣaini sọ diẹ nitoripe ti ẹ ba ṣe iranti wipe emi ti ma nkegbe lati igba de igba pe ẹgbẹkẹgbẹ to ba le ba wa ja ija ati gba Division fun ilẹ Igbomina emi Sanni ti mura tan lati ba ẹgbẹ na ṣe iṣẹ pọ, mo ti mura lọpọ lọpọ lati ṣe iwadi nipa ohun ti wọn da ẹgbẹ Ọdọ Olomi ti wọn ṣẹṣẹ da silẹ nilẹ Igbomina na fun. Mo si wadi lọsan ati lajin oru tobẹ ti mo fi lọ ri Baba ẹgbẹ Ọdọ Olomi na Ọgbẹni Raphael Babaoye lati bere ohun pataki to fi da ẹgbẹ na silẹ. Baba ẹgbẹ na si fun mi lesi wipe, awọn da ẹgbẹ na silẹ fun ilọsiwaju ati anfani ilẹ Igbomina ni, kiṣe pe fun ọtẹ ṣiṣe rara. Lotọ mo ri nkan kan fayọ ninu ero wọn. Ohun na ni pe oruko ti ẹgbẹ na njẹ wọn sọpe ẹgbẹ Ọdọ Olomi tilẹ Igbomina, ṣugbọn wọn ko sọpe ti Oro ni kan ni ẹgbẹ na, nitoripe iti ọgẹdẹ bọ lọwọ Gbẹnagbẹna, Itan Igunnugun bọ lọwọ ẹniti o njẹ ẹran. ẹ o ba jẹki adupẹ to ba je pe ẹgbẹ Ọdọ Olomi yi le bọ ajaga iya to njẹ wa nilẹ Igbomina kuro tabi ti ẹgbẹ yi ba le ṣeto ki ilẹ Igbomina fi gbu ṣọkan, ki irẹpọ le wa lọjọ iwaju.

IWỌN IWE KO ṢE MANI
IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN;
IWE ADURA IṢEGUN AWỌN AJẸ;
IWE IFA AGBỌN-NIREGUN, IWE ITUMỌ ALA PẸLU IWADI NKAN;
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU;
IWE ADURA TETE DA MI LOHUN;
IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢẸDALẸ.

KỌWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Awon omo Eko tun gbe asa buruku de

LATI ỌWỌ:– ADEBINPE ATUNBI
No. 408, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

O ti di asa awọn ọmọ Eko, bi wọn ba ti ri obinrin iba jẹ ọmọde iba jẹ agba ti o ba ti mura dadu, ti o wọ aṣọ tuntun, ṣe ni wọn ma kegbe Aṣẹwo Oforun le lori iru aṣa buruku wo ni eyi, ki Oluwarẹ ma gbọdọ rin ni titi, iru asa bayi ko dara rara

Bẹni ni ọjọ kan, emi pẹlu ọrẹ mi mura a nlọ si ode, ọjọ na si jẹ ọjọ isinmi (Sunday), iru aṣọ kan na si ni emi pẹlu ọrẹ mi na wọ, bi a ti nlọ ni ọna Isalẹ-Eko bẹni a ri awọn ọmọde kunrin kan ti wọn ngba bọlu (Ball), bi wọn ti ri emi pẹlu ọrẹ mi yi, ṣeni wọn nkegbe Aṣẹwo-Oforun, bẹni aṣọ ti a wọ ki iṣe Bonfo rara, o yẹ ki iru awọn ẹni bayi mọ iru awọn ti o yẹ ki wọn bu yatọ si ẹniti ko yẹ.

Asa buruku gba ni eyi, ko d a r a rara, o ti di asa awọn ọmọ Eko, wọn ki nri asa ti o ba d a r a aya fi eyiti ko ba d a r a yen ni wọn ma nri da, ko dẹ nṣe awọn ọmọde nikan ati awọn agbalagba wọn na ni pẹlu Iba a ṣe ẹgbẹ Iya wọn na ni o nkọja lọ, Aṣẹwo-Oforun na ni wọn ma ke le lori, ṣugbọn iru asa bayi ko dara rara. O di gba kan na.

## Awon Oselu ile Naijiria lo be ile Gesi wo



Awọn ẹnia mẹta ninu awọn Oṣelu ilẹ Naijiria ti wọn lọ ṣe abẹwo ilu Gẹsi, ni awọn mẹta ti nwọn duro niwaju Balliol C o l l e g e, orukọ wọn ni wọnyi: Oloye Ọlọla E. A. Anuku, Oloye G o g o Abbey ati Alhaji Ahman Galidiman Pategi.

**Wanted**

An experience Yoruba Editor. Apply in Persons to:-
IROHIN IMỌLẸ
16, Bamgbose Street, Lagos.

## Kini O mo Ni pa Ile Naijiria?

(1) Tani Oyinbo alawọ funfun ti o kọkọ ba wọn bẹrẹ owo Eru ni ṣiṣe, (b) Lọdun wo ni?
(2) Darukọ Baba Ẹgbẹ (P r e s i d e n t) fun ilẹ Niger Republic?
(3) Nibo ni Naijiria ti ri Orukọ ti a nlo yi?
(4) Lọdun wo ni Marry Slessor wọ ọkọ lọ si Ilu Calabar
(5) Nigbawo ni Clapperton de si Ilu Ṣokoto?
(6) Tani Alamojuto fun Eto Alafia ilu Eko tẹlẹ (Health) ki a to Dibo ni Ọdun 1959?
(7) Lọdun wo ni a bi Ayọ Rosiji?
(8) Nigbawo ni wọn bi Dr. Alhaji, Abu Bakar Ibinyinka Ọlọrunnibẹ ti ṣe Mayor Eko tẹlẹ ri?
(9) Lọdun wo si wọn si ọna oju Reluwe lati Eko si Ilu Ibadan?
(10) Wọn si Titi Mọto lati Ilu Ibadan lọ si Ọyọ ni Ọdun — — — ?

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI LOJU EWE KEJE.

## Eyi ni idi ti Amotekun ati Ewure ko fi papo mo

LATI ỌWỌ:– ỌLAYIWỌLA AKANDE
No. 186, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni igba kan Amọtẹkun ati Ewurẹ jẹ ọrẹ timọtimọ, eyi amọtẹkun bi ọmọ meji, ewurẹ na si bi ọmọ meji ọmọ ti ewurẹ dara ju ọmọ ti amọtẹkun lọ, o lẹwa pupọ, nigbati Amọtẹkun ro nkan to le ṣe ti, o gbera o lọ si ile wọn, o sọ fun wọn w i p e, ni ọjọ ti ẹni ẹma ṣe inawo yẹn, emi Amọtẹkun na ma da yin lọla kan ti ẹ o fi ni gbagbe mi, wọn sọ fun wipe a w ọ n yio ma ni ireti rẹ. Inawo na ku ọjọ meje nigbati Amọtẹkun ti pada lọ si i l e ewurẹ, ti on pẹlu Ewurẹ jọ ngbe pọ, bi o ti de ile lo ba sọ fun Ewurẹ w i p e, awọn ma ṣe Iyawo kan ni ile wọn ni ọjọ meje oni, Ewurẹ da lohun pe, ko buru o.

Bi ọjọ na ti ku ọla ni amọtẹkun ti ran ewurẹ lọ si ilu keji wipe, ki o lọ ba on ra aṣọ ti on ma lo wa, bi o ti ri wipe ewurẹ ti jade ni o ba wọ inu ọgba lọ, o mu ọmọ ewurẹ mejeji o di wọn sinu apo o di ẹ n u rẹ pọ. Awo ati Akata jẹ ọrẹ awọn mejeji ti wọn ma nwa ki nwọn, bi awọn mejeji ti mbọ wa-wo alafia amọtẹkun ati ewurẹ, ni w ọ n ba ri Amọtẹkun nibiti o ti ndi ọmọ ewurẹ sinu apo, wọn ko si yọju si, bi wọn ti ri pe amọtẹkun ti wọ inu ile t a n, ni awọn mejeji ba wọ ile lọ, bi ẹni pe wọn ko ri rara fun iṣẹ aidara ti o ṣe, ko pẹ pupọ na ti awọn Awo ati Amọtẹkun wọ ile ni e w u r ẹ ba wọ ile, ni wọn ba ki pe ku abọ o.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸJỌ

ADVT. 211

## Federal Ministry of Finance

GOVERNMENT OF NIGERIA 3¼% REGISTERED STOCK

The above will be redeemed on 1st December, 1961.

A circular Notice has already been sent to all Stock holders at their last-known addresses, incorporating a form of claim for payment.

Any stockholder who has not received such a notice should immediately write to this office, with the request for a form claim for payment.

(Sgd.) R. E. MARSH,
Accountant-General of Federation,
for Permanent Secretary,
Federal Ministry of Finance.

Mosaic House,
Tinubu Square,
Lagos.
1st November, 1961.

## Bi owo Eru ti se bere ni Atete ko se (apa 2)

Lose to koja mo so ni apa kini, bi owo Ẹru ti ṣe bẹrẹ ni atetẹ kọ se, ṣugbọn lọsẹ yi emi yio tubọ ṣe siwaju nipa bi owo ẹru ti ṣe bẹrẹ. Awọn Oyinbo alawọ funfun fi ilu wọn silẹ lati lọ duro nilẹ Amẹrika, nitoripe, nigba ọdọ wọn, nwọn ko ni agbara to lati roko funra wọn, wọn si nfẹ osiṣẹ ti yio ba wọn ṣiṣẹ tabi ba wọn roko.

LATI ỌWỌ:—

**Latifu Babalola**

AKỌWE AGBA ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE.

Awọn Oyinbo alawọ funfun yi kọkọ lọ si Ilu Iwọ Orun awọn India (West Indise) lati lọ ko awọn ara India alawọ pupa lati wa ba wọn roko, ṣugbọn awọn ara India alawọ pupa yi ko lagbara to lati ṣiṣẹ yi, wọn a si ma ku nigbakugba, nitoripe wọn ko le ṣiṣẹ to lagbara ninu orun. Ni wọn ba tun ṣe ipinnu lati ma wa ko awọn enia alawọ dudu lẹru nilẹ Afirika ti yio si ma ba wọn ṣiṣẹ oko wọn ati ninu ohun Iṣura ilẹ miran.

### OWO ẸRU SI ILẸ AMẸRIKA

Owo yi jẹ owo ọmọ enia, awọn oyinbo alawọ funfun olowo ẹru wọnyi yio wa silẹ Afirika pẹlu ibọn ati ẹtu ibọn, ọti gin ati awọn orişirişi irinṣẹ ti wọn (Instruments) yio si fi ṣe pasiparọ fun ẹru enia dudu.

Ninu ọdun 1503, awọn Spaniards bẹrẹ lati ma wa ko ẹgbẹrun ẹru lọ si inu oko ati ohun Iṣura nilẹ Amẹrika, awọn Potogi kẹ. (Portugueese) yio mu ọkọ wa lati wa ko ẹru lọ si ilu Brazil. Ninu ọdun 1562, awọn Oyinbo alawọ funfun akọkọ ti yio kọkọ bẹrẹ owo ẹru ni Ọgbẹni John Hawkins, o lọ si ilu Saro (Sierraleone) nibiti o gbe ti lọ ko ọdunrun ẹru lọ si inu oko awọn Gẹsi nilẹ Amẹrika.

Nwọn si ma ra awọn enia Dudu lẹru pẹlu, gbogbo awọn ẹru ti wọn ba ko lati ilẹ Afirika lọ si ilẹ Amẹrika yio ma lọ ṣiṣẹ ninu oko ireke tabi oko taba awọn ara Brazil. Gẹgẹ bi mo ti sọ siwaju pe, Ọgbẹni John Hawkins ni Oyinbo Gẹsi ti o kọkọ bẹrẹ owo ẹru, lẹhin igba na ni awọn ilu Spaniard, French, ati Dutch to bẹrẹ, ki wọn to sọ di ijadu tabi idije (Competition). Ile olodi ati ile iṣọ ni wọn kọ si eti okun tabi agbegbe Iwọ Orun Afrika lati le tọju ati dabo bo awọn ẹru ki ọkọ ẹru to de, nipa eyi, awọn Oyinbo na nṣe ninu owo ẹru na pẹlu, awọn Potogi lo kọkọ wa ko ẹru ni Iwọ Orun Afrika.

### IRU IYA ATI ISẸ TI WỌN NSE FUN AWỌN ẸRU

Eyi ni bi wọn ti ṣe nfi iya jẹ awọn ẹru, wọn yio fi wọn sinu oko ireke tabi oko taba, awọn miran yio si ma wa ohun Iṣura ilẹ lati ma wa Gold jade, wọn koni jẹun lati owurọ titi di alẹ, nṣeni wọn ma nde wọn lẹnu pẹlu agadagodo nitoripe ki wọn maa le ri ayè mu ireke tabi taba.

### OHUN TI O FA OWO ẸRU NI WỌNYI

Awọn Oyinbo ti wọn lọ si ilu Amẹrika ṣe ibujoko nfẹ ẹru ti yio ma ba wọn ṣiṣẹ, nitori wọn ko ni agbara to lati ṣiṣẹ rara. Awọn ara ilu Spanish ti wọn wa ni Iwọ Orun India Island, ti wọn si nṣe iyọ oyinbo (Sugar) wọn nfẹ ẹru ti yio ma ba wọn ṣiṣẹ ninu ile iṣẹ wọn.

Awọn ti wọn ma nko lẹru nigbana ni awọn, Onigbese tabi Arufin, ati awọn ti wọn ba ju si ẹwọn logun, ti wọn ba si ko wọn tan, wọn yio ko wọn si ẹgbẹ kan titi ọkọ ẹru yio fi de.

Lose to mbọ lagbara Ọlọrun ẹ o tun ma gbọ bi wọn ti ṣe da owo ẹru duro ati awọn ti wọn da duro. Ki Ọlọrun sọ gbogbo wa di ọsẹ to mbọ o, ki o si fi ibukun rẹ sori iṣẹ Olukuluku wa o Amin.

## Dr. Asikiwe ati Dr. Kenneth nmu faaji



Awọn ti a nwo ninu iwe yi ni Dọkita Nnamdi Asikiwe Gomina Agba fun ilẹ Naijiria ati Dọkita Kenneth Dike, nwọn mba ara nwọn mu faaji ọrọ sisọ ninu Gbọngan (Hall) ile ẹkọ giga University College Ibadan. (Wo aworan wọn miran loju ewe Karun)

## Omo Alufa lo ko Eko nilu Oyinbo



Ọkunrin ti a nwo ni apa ọtun ti o nfi ohun kan han Ọmọbinrin yi ni Alagba Ọlọla Arthur Kirby on ni asoju agbegbe Ila orun Afirika nilu Oyinbo on lo mba Sinabu ọmọ bibi inu Alufa Kassim Abudu Hafisa ti o ti ṣe Alufa ile ẹkọ nla kan nilu Sansibar sọrọ.

# Ajẹgboro dagba

GBOGBO Nyin ni mo ki emi ko ni olodi kankan, mo ki ẹnyin ti ẹ duro ẹ ku iduro, ẹnyin ti ẹ joko ẹ ku ijoko, mo de emi a tu wọn ka nibiti nwọn si nda ina irọ, emi a le wọn danu nibiti wọn gbe di Rogimo bu Ọmọ abinu fi panla ṣile meji jẹun yo. Alatako awọn ọmọ Jaiye jaiye, mo tuu de si ẹnyin alaṣaka ilu eko lowurọ yi.

IRU AṢA WO TUN LE YI O! AṢẸWO KOFO'RUN

Nigbati a ti gba Ominira, ko yẹ ki a tun wu wa bi Ilu ti ko ti laju, tabi kia ma laju ala sodi, papa larin Ilu Eko ti o jẹ Olu-Ilu Naijiria lati ma da aṣa kaṣe ti ko tọ. Obun na ni ofa ọrọ mi ti Ọsẹ yi, Jọwọ lọwọ-lọwọ ti o nkawe Iwe mi yi lọ fi silẹ kise ohun ti o tọ, aṣa na ni pe bi awọn Olomoge Obinrin lomọde tabi Agba ba ti mura ti osi nlọ si ode, ni iwọ yio ma gbọ ifẹnu tomọde tagba lọkunrin pe "AṢẸWO KOFORUN,, ti wọn yio si ma gba lọtun ati losi ti o fi jẹ pe oju yio ti onitọhun ti o mura, wọn ko si ni fi oju pamọ rara, nwọn yio si ma kigbe titi iwọ na yio fi mọ pe iwọ ni nwọn nba wi. Laipẹ yi nigbati emi pẹlu Adiyatu mi nlọ si ode lọna Adugbo kan ti o gbajumo leko, bi a ti yọ si Adugbo na ni nwọn bẹrẹ si ki gbe lọtun ati losi wipe "O FORUN,, ati ọmọde ati agba lo si nkigbe nwọn kigbe yi titi emi na fi mọ pe Iyawo mi ni wọn nba wi Iru aṣa bayi ko dara rara, ki enia ma le rin, ma le mura larin Ilu Eko, nigbati a si sọ pe Aiye ti di aiye Ọlaju, ti a ko si, si ni Ilu awọn atinhoriho, Ilu wa si ti di Ilu Ominira. Mo fẹ bere lọwọ gbogbo ẹnyin ti ẹ nda aṣa buruku wọnyi, ati ti ẹ nda silẹ, kini ere ti ẹ nri nibẹ, tabi iru ipo wo lẹ wa lati ọjọ ti ẹ ti nda, Aye wo ni Ijọba fi yin si? Ẹko ri nkan gba nidi reju epe lori lọ, orin ti ẹ ko kọ lati owurọ titi di alẹ ti ẹ ko ri enia ki yin tabi fun yin ni kankan kini ṣe ti ẹ ko fi jawọ ninu rẹ, gbogbo ẹgbẹ yin nwa ọna bi on yio ti se ri owo saiye, aṣa ni iwọ nda kiri, stilẹ gbọ ti ọmọde, e wo lo kan Agbalagba, ma danu ti o gbenu si oke kiri, o foru i kini Itumọ rẹ.

Aṣa kọ lo yẹ ki ẹ ma kode, ohun ti o yẹ tọmọde tagba awa enia Naijiria ni pe bi Ilu awa yio tise tun ma laju si, tabi ti yio si tiṣe jawọ ninu awọn iwa buruku ati iwa Okunkun eyiti o kun ilẹ wa lode oni, Aṣa buruku kọ tọ silẹ Naijiria rara, ẹ jẹki gbogbo wa panupọ ki a wa Ilọ Siwaju fun orilẹ-Ede wa o, Aṣa kọ lo yẹ wa o.

Nitorina, ẹ jọwọ mo bọ yin, iwọ ti o ba nda aṣa yi, ki olọ fi silẹ, ki o si ma kilọ fun ọrẹ rẹ ti onda, Iro la fẹ fun Naijiria nisisiyi papa ni Ilu Eko ti se Olu—Ilu rẹ gbogbo yin ni ẹ si mọ pe ojojumọ la gba alejo lati ilu Okere ti wọn wa bẹ ilu wa wo ko wa ṣe pe iwa buruku tabi aṣa ti ko da ni wọn ba lọwọ wa, kini iwọ lero pe won yio tiṣe lọ sọrọ iluwa bi wọn ba pa da de lie. E maṣe doju ti ilẹ Naijiria o.

Mo fi iwe mi yi kẹwọ lati kesi Alamojuto eto alafia ilu eko ati awọn Ọlọpa pe ki won ma moju ilu dada ati pe ki nwọn ma ma gba awọn enia laye lati ma ko aṣa buruku iru eyiti ko fa alafia fun ilu, ki wọn mu ki nwọn si jẹ niya nitori iru awọn enia bẹ ko fẹ ire ati alafia fun ilu ni yẹn.

## Dokita Nnamdi Asikiwe nile eko Giga University College Ibadan



Ẹniti a nwo ni iduro ti o wọ aṣọ awọn Olukọ ile ẹkọ giga University College ni Ọlọla Gomina agba Dr. Nnamdi Asikiwe ti o mba awọn ọmọ ile ẹkọ giga University College Ibandan sọrọ nigbati nwọn pari idanwo wọn ninu ile ẹkọ na, nwọn si nfun wọn ni oye ẹkọ wọn. Ẹniti a nwo lọwọ osi ni Ọgbẹni Dọkita Kenneth Dike ti iṣe Olukọ agba ni University College Ibadan. Ẹniti o si joko lọwọ ọtun ni Dr. Okesuku Ikejiani ti o jẹ Alaga igbimọ ile ẹkọ na.

# Olofofo

E ku airi ni aibe re ẹni, ẹ si ku ipalẹmọ ọdun Keresimesi t'ombọ laipẹ yi jojọ, Oluwa yio jẹki a peju ṣe ọdun na pẹlu ayọ ati inu didun. Amin.

Ki nto ma ba ọrọ mi ti ọsẹ yi bọ, o tọ, o si yẹ ki nki gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ wipe ẹ ku ẹjọ mẹta.

Mo si wa dupẹ gidigidi lọwọ awọn Oludasilẹ iwe Irohin ni ede Yoruba papa iwe Irohin Imọlẹ eyiti o wa fun orisirisi ati oniruru enia, eyiti ko wo oju tabi Ọgba lati gbe ọrọ e ikẹni jade eyiti ko ba ti lodi si ofin rara,

## Lati Owo:- Omo "Ade"

Lati ọjọ ti iwe Irohin Imọlẹ ti di oju mẹjọ o dun mi pupọ pe nko ni anfani lati igbana lati le ma fi Olofofo mi han ẹnyin Ọnkawe wa gbogbo, ṣugbọn lati isisiyi mo ti gba ni adura si ọdọ Olodumare pe emi yio ma mu yin larada nitoripe Olotu Ọgbẹni Adeniji ti fi aye silẹ fun mi lọsẹsẹ.

Nitorina mo bẹ gbogbo ẹnyin Ọnkawe wa patapata ẹ maṣe jẹki kobọ meji (2d) ọsẹsẹ wọn olukuluku nyin. Idi rẹ ni eyi

Awọn Oludasilẹ Iwe na fi aye silẹ fun awọn Ọdọmọde laye lati le ma kọ Ọgbọn ati Oye wọn, nitoripe gbogbo ẹnyin obi ti ẹ ma nkawe Irohin ni ede Oyinbo ti ẹ si nṣe Idawo ni o ma njẹ wipe nigbamiran ninu Irohin ni Idaji Ibere ti njade, gbogbo Iwe Irohin ni wọn si jọ ni OFIN kan na pupọ ninu Irohin ti o njade ninu awọn Iwe ni o jẹ lati ọwọ Ijọba.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA.

# ORO NIPA IGBAGBO

Lati Ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE

Mo fẹ ki ẹ mọ wipe ohun gbogbo ni sisẹ fun ẹniti o ba gba Ọlọrun gbọ, lori igbagbọ ni ohun gbogbo ti wa nibẹ ni alafia tiwa pelu, nitoripe ile ti Ọlọrun ko ba ko awọn to nkọ ile na nsisẹ lasan ni, bi ko ṣe pe Oluwa pa ilu na mọ, Olusọ nji lasan ni asan ni fun ẹnyin ti ẹ dide ni kutukutu owurọ ti ẹ ko Oluwa sile orin Dafidi 127-1

Nitorina gbogbo awa Onigbagbọ ẹ jẹki a mọ ohun ti a nṣe, maṣe jẹki Keferi ju wa lọ lọdọ Ọlọrun, nitoripe Iwa irọ, iwa Agbere, iwa eke ko yẹ fun Onigbagbọ mo fẹ ki ẹ ro ọrọ yi wo gbogbo ẹnyin onigbagbọ ko si ẹmi Ọlọrun ninu wọn, wo o iwe korinti orin 5, ẹsẹ 1, o sọ bayi pe ati rohin rẹ kalẹ pe agbere wa larin yin.



WOLI KOGBEREGBE

Iru agbere ti a ko gburo rẹ larin awọn Keferi pe okan ninu nyin fẹ iyawo baba rẹ nje iru iwa bayi dara fun Onigbagbọ bi? Ko yẹ ki Onigbagbọ ma gbadura nipa owo ni gbagbogbo, owo ni gbongbo ẹṣẹ fun Onigbagbọ, nitori bi Onigbagbọ ba fi fẹran owo ju yio ṣẹ Ọlọrun. Nitoripe ninu owo ni buruku ti wa beni ero ika iro ole, ẹniti o fi ọmọ ṣe owo, ta lo da iwa wọnyi sile? Owo ni. Mo fẹ ki gbogbo yin mọ pe kosi Igbagbọ mọ ẹtan lo kù, nitori ọpọlọpọ ninu onigbagbọ lo ti fi ọmọ enia ṣe owo, o si bẹrẹsi kọ ile, o bẹrẹsi ra mọto, o kọ petesi, o ra ile, o si bẹrẹ si yọkun pẹlu, o wipe ibukun Oluwa ni, e jọwọ ẹ dahun si ọrọ yi, Njẹ ibukun Oluwa niwọnyi bi? kiyesi o nrobi ẹsẹ, o si loyun iwa Ika o si bi eke jade, orin Dafidi 7, ẹsẹ 14, mo fẹ ke mọ pe olowo kan ko le de ọdọ Ọlọrun lailai, nitoripe o ti gbe ọmọ rẹ ṣe owo, nigbati olowo ba de ọdọ Ọlọrun yio si wipe, e lọ kuro lọdọ mi ẹnyin oniṣẹ ẹṣẹ, oju yio ti gbogbo wọn lojọ na, ara yio si kan wọn gogo, nwọn o pada, oju yio ti wọn lojiji. Ori Dafidi ori 6 ẹsẹ 8.

Read The IROHIN IMOLE every week. It is a Yoruba Weekly Paper that will provide you with more News more Pictures and more Fun. It will enlighten, entertain and inform you. Always read:-

**"Irohin Imole"**

The most exciting controversial Yoruba weekly Paper

## OBERE LATI OJU EWE KARUN

Nitori Idi eyi enikeni tabi Orilẹ edekede ti o ba ni Anfani ti awọn YORUBA ni yi inu wọn ni lati ma dun ni, nitorina awa YORUBA ti a ko mọ ede Oyinbo ka ẹ jẹki a ma ka awọn Iwe Irohin YORUBA, ELETI-ỌFẸ, IMỌLE. Mo nbi ẹnyin Ọmọ Yoruba lere ọrọ, Ilu wo lo tun ni anfani lehin ede Oyinbo ti iwe Irohin wọn njade Ayafi ede Yoruba nikan. Ẹnyin ọkawe wa mo fẹ ki a fi ọwọ sowọpọ lati dupẹ lọwọ awọn Oludasilẹ awọn Iwe Irohin wọnyi nitoripe ede Yoruba sọrọ diẹ dajudaju ọrọ ti o nbẹ ninu awọn Iwe Irohin wọnyi ni ọsọsẹ ju Kọbọ meji (2d) ti ẹ fi nra lọ.

## MO KI AWỌN ALABOJUTO NI ỌJA MUSHIN MO WA DUPẸ TEMI.

Bi a ba ṣe ni lore ọpẹ ni o ye awọn ti a ṣe e fun nitori idi eyi ni oruko awọn Olugbe Mushin ati agbegbe rẹ emi Ololofo dupẹ pupọ lọwọ yin pe ẹ ku Ọgbọn ati Lakaye ti ẹ fi ndari iṣẹ yin iwaju ni ẹ o ma lọ ile yin yio roju ọna yin yio si raye, A dele ba re, Arinna kore Akoya Ibi ni tiyin. Gele ko dun bi ki a mọ we Ewa ko dun bi ki a mọ wọ ki a mọwe ko dabi ko yẹni yẹni ko dabi ki a ri owo ra, ki a ri owo ra ko dabi ki a mọ lo. Awọn alabojuto ti o nbẹ ni Mushin District Kansulu nisisiyi yẹ ni ẹniti a le sọ fun pe awọn ni ki awọn maṣe iṣe na lọ nitoripe iṣẹ wọn ntanna Imọlẹ kakiri gbogbo agbaiye wi ni nkan bi ọsẹ mẹta sẹhin ni mo wa ninu ọkọ Reluwe ti awọn kan nsọ wipe lẹhin ti wọn ba ṣe Oja Mushin yio jẹ ọkan ninu ọja ti ko si ekeji rẹ ni ilu West Afrika. Nitorina mo bẹ ẹnyin Alabojuto na pe ki ẹ tun bọ mura si iṣẹ yin na nipa ọna Mọto ( R o a d s ) si gbogbo ibi ti e tọ ti o si yọ, nitoripe Oruko buruku ti nwọn n pe Mushin ko dara rara, gbogbo awọn ọmọ JAGUDA PALI ti o wa lati ilu miran ni wọn wa fi Mushin ṣe Ibugbe ki ẹ fun awọn Ọlọpa Mushin ni Ofin ti o tọ nitoripe Oruko rere san ju Wura ati Fadaka lọ ẹ jẹki Mushin jẹ eyiti a o ma ga ọrun wo laipe jọjọ. Agbefo ni ti ọmọ "Ade,,

Ni Ọse to mbọ ẹ o tun gbọ ọrọ.

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




OLUBORI EGBOGI "IKỌ

# THIOLYPTINE.

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni Thiolyptine ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ofun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ lile, Ikọ' ti o ma mu enia tu kẹlẹbe nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi Thiolyptine yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.

Bere egbogi yi ati awọn orisirisi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

Price 10/6 Postage 3/-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

## Aseju Baba Asete.

Lati Owo:- Eni Owo Omo Aridegbaju Oke-Ola Oro.
O BERE LATI OSE TO KOJA.

Nitoripe ibi towa tele bosi horo, kosi lemu Ilosi waju ba Ijoba wa, oinun ti mo fe ki o ye gbogbo enyin oluka mi nipe, kise Oke Ola nikan lenfa oro oja yi, beni kise Ijomu nikan, kisise Iludun nikan pelu, gbogbo awa ti ani asoju nile igi imo ibile Oro, ti asiję Omo Egbe N. P. C. lafe ki oja baba gbogbo wa na kuro ni otun Oro, ki o si bosi Oke ȩdo Oro, ni idi eyi, awon Otun Oro ngbidanwo lati yi ero awon Igbimo Ibile Oro yi pada, won nawo, nara, won nlo si ilorin, won nbo, nigbati won ripe epakoboro mo, won wa se ipade pajawiri kan, won ni ohun to dara fun awon lati se nigbati owo awon ko te oja mo yi nipe, ki awon bere sile awon omo Oke Ola, Iludun, Ijomu to ba wa lodo awon kuro, nisisiyi won ti bere sile won kuro ni odo won, won wa gbagbe pe ni oro ti Olorun ti da eria lou da ohun ti yio je ti i, won fi lile ni kuro yi pe Olorun nija (Challenge) Olorun Olodumare mase bawa ja, Sugbon ero wonyi kuru loju temi Ohun ti won ibase nipe, gbogbo omo Oke Ola o, Iludun ati Ijomu Oro, ti ti won fe niyawo ti osi ti bimo fun won, ki won kowon niyawo ki won ko omo won na patapata pelu, Igbana lato wa mope won nbawaja laiko se Ohun ti mowiyi, ako mope won nba waja rara, Ha! ha, A nge yin lowo esi tun bo oruka se ote sise yi ekowa le fisileko tabi bawo? beni ohun ti awa nfe nipe, kio mase si ija mo kio mase ote mo, Esi fe dekun ote na Ejinna si aseju emase lo si irin ajo biti aseju. Eyin enia mi gbogbo Omuaran ni mo ti ko yi, ti mobati ti oruko iye awon omo wa ti won lekuro gba, ati oruko iye awon eni to lewon, ti o bati temi lowo e o ma ri won ninu iwe Irohin Imole, Daily Times, pelu ogo Olorun Oba, ti ti mo ba de lati irin ajo mi mi o royin bi won ti bere si se mi lalejo kie toju kobo meji lowo (2d) ni ojo Monday.

IYOKU DI OSE TO NBO.

## Ogagun kan yo mo iya re, nigbati o de lati Kongo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Lieut Col Ademulegun ti ise okan ninu awon O g a g u n ile Naijiria ti o sese pada ti Ogun de lati ogun ile Kongo ti o si diro mo iya re. Sa wo o, ife ti Obi ni si omo, o diro mo, o si fi enu ko ti enu.

EYI NI IDAHUN AWON IBERE TO WA NI OJU EWE KETA

(1) John Hawkins (b) Lodun 1562 (2) Hamani Diori
(3) Ni Odo Niger (4) Lodun 1876
(5) Lodun 1824 (6) Ayo Rosiji (7) Febuary, 1917,
(8) September 20, 1908 (9) Lodun 1900
(10) 1905.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O SESE DE TI WON NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJEBIDAN FUN AGBALAGBA OKUNRIN GBOGBO




Dynamiren je Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awon Jamani ti nse wa fun tita ki ogun (War) ti awon Gesi pelu won to sele. Lehin igbana a ko ri irufe egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti ise re si daju be yen mo ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranse si awon Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki won se iwadi awon elegbogi "Dynamiren" bi won ba si mbe laiye. Won si da esi pada wipe won nbe atipe egbogi na ti a nfe lodo won wa pelu. Eyi mu inu wa dun pupo julo nitoripe awon Onibara wa mo daju wipe kosi asanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Egbagbeje irufe re wa kakiri sugbon bi ti eleyi ko Bi are ara ba mu o, nigbakugba fun wahala tabi ise ise ti o ko ba le jeun daradara, tabi ki o ma le sun dekon losan tabi loru tabi awon "Isan ara re gbogbo" ko ba sise daradara areE-emi (breath) inu ko ba gunle dara dara to nitoripe ise tabi wahala sise ko "NJE" fun won ailera gbogbo wonyi ti ojo ori re (age) ba ti koja ogbon o d u n lo si dede adorin tabi jube lo mo daja pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfe lati so ara re di Otun patapata, oju re a si jolo, eran ara re ti o ti hunjo yio bere si dan pada. Ara re yio ma gbe kookon nigba kugba "Are" nigbakugba yio salo patapata pelu.

Igbadun ati Alafia yio de si o.

Bere egbogi na ni Sobu awon:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

Bere egbogi yi ni Sobu awon:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWON SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE OYO IBADAN

## Ma a ka Irohin Imole

## O BERE LATI OJU EWE KETA

Won ni ṣe dada lọ de o, nigbati awọn Awo ati Akata ri aṣọ lọwọ Ewurẹ, ni wọn ba bere ohun ti o fẹ ṣe, lo ba sọ fun wọn wipe awọn fẹ ṣe inawo kan ni. Amotẹkun na ba sọ fun wọn wipe ki wọn ma sai wa o, bi wọn ti ṣe ma lọ ni Amotẹkun ba ni ki Ewurẹ sin wọn jade, ni Awo ati Akata ba sọ fun Ewurẹ wipe, ki o mọ bi o ti ma yọ awọn ọmọ rẹ kuro ninu apo, Ewurẹ ba sọ fun wọn wipe, on ko ni ona kankan, nitoripe awọn mejeji ni awọn jọ nsun. Awo ba sọ fun Ewurẹ wipe ko fi ọkan balẹ, wipe bi o ba ti di oru on yio fo wọnu ọgba lọ lati lọ tu awọn mejeji na silẹ.

On yio wa ko ọmọ tirẹ sinu rẹ, Akata ni Awo sọ fun wipe bi on ba ti mu awọn ọmọ Ewurẹ kuro, ọmọ ti Amotẹkun ni on ma fi si i, bi ilẹ ọjọ na ti su tan ni Awo ba fo wọ inu ọgba lọ, lo ba tu ọmọ Ewurẹ silẹ, o si ko ọmọ Amotẹkun sinu rẹ pada, bi ilẹ ọjọ keji ti mọ tan ni gbogbo wọn ba mura tan lati ma lọ, ni Amotẹkun ba sọ fun Ewurẹ wipe ki o ba on gbe apo ti on gbe silẹ yẹn dani, nitoripe nkan ti awọn ma jẹ lo wa nibẹ, bi iyawo inu ile, Ewurẹ gbe bo ti ṣe wi. Bi wọn ti gbe apo na de ibi inawo na ni Amotẹkun bani ki wọn ba awọn gbe omi gbona kana, awọn ti wọn si wa sibi Inawo ti wọn ti nreti nkan to ni of fẹ ṣe, bi omi ti ho tan, ni wọn ba pe wipe o ya o, Amotẹkun ba ni ki Ewurẹ ba on gbe apo yẹn fun wọn ki wọn ba on gbe sinu omi ti o ho yẹn, bi awọn Awo ati Akata ti ri wipe wọn ti gbe apo yẹn sinu omi gbona, ni wọn ba pe Ewurẹ wipe o ya ki awọn ma lọ ati wipe ki o lọ palẹ mọ kuro ninu ile wọn ki o si salọ, ni awọn mẹtẹta ba salọ, bi Ewurẹ ti palẹ mọ kuro ninu ile ni o ba fori si ọna igbo. Ni Ewurẹ ba di ẹaiti o ngbe inu igbo.


## Iwo ha Nfe Igbega bi?

Fun anfani awọn ti o ngbe Eko, ti ko le wa sile wa ni Mushin, ni aṣe kọ awọn apakan ninu ọja wa Nọmba 16 Bamgbose Street Lagos, ẹnikẹni ti o ba fẹ ọja wa ni Eko ki o ma lọ sibẹ.

TURARI AJEBIDAN AGBABIETU

Turari yi ko ni ẹgbẹ akose fun awọn ajẹ ni kan, ti o ba loo iwọ ko ni mọ aita ọja. Adura rẹ yio si ma a gba awọn enia buruku aiye ko tilẹ ni lagbara lori rẹ onsiẹ to igba ọna (200 ways) fun igbega ọmọ enia ni Aiye. (Pangolo 10/6d)

MANAGER (J. O. SHOYINKA.) c/o IROHIN IMOLE
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.



BERE OJULOWO EGBOGI WONYI:

### "Congreve Female Remedy"

Gbogbonse fun Itoju tabi Ajo Obinrin fun Inu rirun Ibadi riro tabi gige nigbakugba, ati orişirişi arun tabi amodi ti o ma nyọ Obinrin lẹnu ni Inu nigbakugba.

### "Collomack"

Egbogi awọn Jamani ti o dara julọ fun Itanpara, awọ ESE lile, Igbado ẹsẹ ti ki jẹki enia le wọ bata (Corn-cure) ati orişirişi arun Ese miran pẹlu ni.

### "Mackotal"

Atamatase Egbogi awọn Jamani fun orişirişi amodi "ETI" riro tabi didun fun ọmọde ati agbalagba bi o ti wun ki ojọ rẹ ti pẹ to yio se iwosan rẹ ni kiakia.

Bere ni Sọbu:

**Waterloo Medicine Stores**
**8, PalniChurch Street, Lagos**
**P. O. Box 333, Nigeria Phone: 22878.**



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN PE NI:-

## RICHALT

FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi y lọ patapata si awọn Robi-robi Isẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ k ṣi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TONIKI Ejẹ ti wọn si nta kukiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo, Iyọn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti a ntanṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse, ati ti awọn Tatabulu si Itali jẹ. Mọ daju pe bi Ejẹ ara ko ba mọ daradara awọn amọdi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ Lakuregbe, orişirişi Inarun Ojuşişu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Aya didun Itanpara, ekuru lara.

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apo ile itọ ẹhin didun tabi Ibadi riro pẹlu egbogi Risaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ejẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ ara rẹ mọ tonitoni pẹlu. Şa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

Bere egbogi yi ni Şọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja itu Faji)**

ATI NI AWỌN ŞỌBU IBADAN:-
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN



## KERE O! Akiyesi Pataki

### Antoin Tablets! Antoin Tablets!!

Ẹyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Eku afojuba egbogi pataki ti a ṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ojogbọn Onişegun (Specialist) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o şopọ ni isisiyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFO TULU LUKULUKU, OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO, ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO. Jọwọ danwo abion ni ogun yi. Irohin ko to afojubo.

Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin: O daju haewun. Ẹ o ri işẹ rẹ lẹhin işoju medogun ti ẹ lo, Bere lọwọ Onişegun adugbo rẹ.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Sreet Phone: 23457

LAGOS


Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21985. Olotu E. A. Adeniji 51, Tejuosho Street, Suru-Lere YABA